# ISỌJI KAN NI JERUSALẸMU

**2 Kronika 30:1-27; 31:1-21**

**ẸKỌ 340 --- FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Ẹ fi ogo fun OLUWA, ti o yẹ fun orukọ rẹ̀; ẹ ma sin OLUWA ninu ẹwà iwa-mimọ́" (Orin Dafidi 29:2).**

**Irannileti**

Ni ọjọ nla ni ti awọn Ọmọ Israẹli fi Egipti silẹ patapata, Ọlọrun dá ajọ kan silẹ ti a n pè ni Ajọ Irekọja. Wọn ni lati maa ṣe ajọ yii ni ọdọọdun lati rán awọn Ọmọ Israẹli leti oore Ọlọrun si wọn ni mimu wọn jade kuro ni oko-ẹrú.

Ọpọlọpọ ọdun ti kọja lọ lẹyin ọjọ yii, awọn Ọmọ Israẹli kò si pa ajọ yii mọ́. Ki i ṣe pe wọn gbagbe igbalà nla yii nikan, ṣugbọn wọn ti gbagbe Ọlọrun tikara Rẹ̀. Dipo ki wọn sin Ọlọrun, wọn n sin oriṣa; Ọlọrun si rán idajọ gbigbona si wọn nitori ẹ̀ṣẹ wọn.

Awọn orilẹ-ède ajeji wá si ilẹ Kenaani wọn si kó ọ̀pọlọpọ ninu awọn Ọmọ Israẹli lẹrú. Mose ti sọ fun awọn baba nla wọn pe eyi ni ohun ti yoo ṣẹlẹ̀ si wọn bi wọn ba kọ Ọlọrun silẹ. Mose sọ ọ̀pọlọpọ ibukun ti yoo jẹ́ ti wọn bi wọn bá gbọran si Ọlọrun lẹnu; bakan naa ni o si tun sọ ègún ti yoo wá sori wọn bi wọn kò bá gbọran (Deuteronomi 28). Kò si ẹni ti o le ṣàigbọ́ran si ofin Ọlọrun ti ki yoo jiya. Ijiya le ṣai de lẹsẹkẹsẹ, ṣugbọn mọ̀ daju pé ẹ̀ṣẹ rẹ yoo wá ọ ri.

Israẹli kọ eti didi si gbogbo ikilọ wọnni, wọn sin ọlọrun miiran, bẹẹ ni ègún ikólọ si igbekùn si ṣẹ si wọn lara. Ọlọrun ti kilọ pe: "OLUWA yio si mu ọ di ẹni ikọlù niwaju awọn ọtá rẹ: iwọ o jade tọ̀ wọn lọ li ọ̀na kan, iwọ o si sá niwaju wọn li ọ̀na meje: a o si ṣi ọ kiri gbogbo ijọba aiyé" (Deuteronomi 28:25). Ọrọ wọnyii bẹrẹ si ṣẹ si wọn lara diẹdiẹ to bẹẹ ti o fi jẹ pe ni ọjọ oni, a le ri awọn ọmọ wọn ni gbogbo orilẹ-ède kaakiri ayé.

**Aanu Ọlọrun**

Aanu Ọlọrun n tọ awọn eniyan Rẹ̀ lẹyin ninu idaamu wọn. Nigba ti ògo Israẹli de gongo ni akoko ijọba Sọlomọni, Ọlọrun ṣeleri pe bi awọn eniyan tilẹ kọ Oun silẹ ti Oun si jẹ wọn niyà, sibẹ bi wọn bá rẹ ara wọn silẹ ti wọn si gbadura, bi wọn bá ronupiwada, Oun yoo dariji: "Bi awọn enia mi ti a npe orukọ mi mọ́, ba rẹ ara wọn silẹ, ti nwọn ba si gbadura, ti nwọn ba si wá oju mi, ti nwọn ba si yipada kuro ninu ọ̀na buburu wọn; nigbana ni emi o gbọ́ lati ọrun wá, emi o si dari ẹ̀ṣẹ wọn ji, emi o si wò ilẹ wọn sàn" (2 Kronika 7:14).

Ma ṣe gbagbe pe O sọ wi pe wọn ni lati yipada kuro ninu ọ̀nà buburu wọn bi wọn bá fẹ́ ni ibukun Ọlọrun. Ọpọlọpọ eniyan ni òde-oni ni o lero pe wọn le jẹ́ Onigbagbọ́ ki wọn si maa dẹṣẹ sibẹ. Jesu wi pe, "Mã lọ, má dẹṣẹ̀ mọ́." Bi ẹnikẹni ba fẹ́ ni ibukun Ọlọrun, o ni lati ronupiwada ki o si yipada kuro ninu ẹṣẹ rẹ̀. Didun inu Ọlọrun ni lati gbọ́ ki eniyan gbadura wi pe, "Ṣaanu fun mi, si dariji mi" bi awọn ọ̀rọ wọnyii bá ti odo ọkàn jade wá.

**Ododo Hesekiah**

Awọn ọba buburu ti mú Israẹli ati Juda dẹ́ṣẹ̀. Lati igba ti orilẹ-ède yii ti pin si meji, kò si ọba rere ni Israẹli. Ṣugbọn Juda ni anfaani lati wà labẹ awọn ọba rere diẹ. Nigba ti Hesekiah bẹrẹ si jọba ni Juda, "O si ṣe eyiti o tọ́ li oju OLUWA, gẹgẹ bi gbogbo eyiti Dafidi, baba rẹ̀, ti ṣe" (2 Kronika 29:2). Wo iyipada ti eyi mu bá Juda! Wọn gbá Tẹmpili, wọn si tun pada si isin otitọ Ọlọrun lẹẹkan si i. Eyi mú ki inu awọn eniyan ki o dùn.

Hesekiah mọ̀ nipa ofin Ajọ Irekọja ti a fi lelẹ niwọn ẹgbẹrin ọdun (800) sẹyin. Inu rẹ̀ bajẹ pe a kò pa àjọ yii mọ́ fun ọdún pupọ. O fẹ ṣe ohun ti Ọlọrun palaṣẹ, nitori naa o fi iwe ranṣẹ, ki i ṣe si kiki ẹya Juda ti o n jọba le lori nikan, ṣugbọn si gbogbo Israẹli pẹlu, o si pe wọn lati wá si Jerusalẹmu fun Ajọ Irekọja.

Hesekiah kò beere pe ki awọn eniyan Israẹli dara pọ̀ mọ́ ijọba oun, ki wọn si ṣeleri lati fara mọ́ oun. Akoso ijọba kọ ni o ṣe pataki fun un bi iṣẹ-isin Ọlọrun. O fẹ ki a gba ọkàn awọn enyan naa là, ki wọn ba

le lọ si Ọrun ki wọn si ni ìyè ainipẹkun. Akoko wa nihin kúrú pupọ, o si ṣe pataki fun wa lati lo akoko wa lati mura silẹ fun ayeraye.

**Ọjọ Ajọ Naa**

Ofin ti a fi fun Mose ni pe a ni lati bẹrẹ ajọ yii lati ọjọ kẹrinla oṣu kin-in-ni. Wọn ni lati ya ọdọ-agutan fun ẹbọ naa sọtọ tẹlẹ ki wọn ba le ni anfaani lati ri i bi abuku ba wà lara ẹran naa laaarin ọ̀sẹ̀ meji wọnni.

Gbigbá Tẹmpili ati yiya awọn alufaa si mimọ́ jẹ ohun ti a ni lati mu ṣe laaarin akoko kukuru to bẹẹ ti kò fi si anfaani tó lati ṣe gbogbo imurasilẹ. Mose ti sọ tẹlẹ pe bi ko ba ṣe e ṣe lati pa ajọ naa mọ́ ni oṣu kin-in-ni, wọn le ṣe e ni oṣu keji. Hesekiah bá awọn ijoye ati diẹ ninu awọn ijọ eniyan gbimọ̀, wọn si pinnu lati pa ajọ yii mọ́ ni oṣu keji. Wọ́n fẹ́ lati ni idaniloju pe nigba ti wọn ba wá siwaju Ọlọrun lati jọsin, wọn o wà ni ipò ti Ọlọrun yoo fi bukun fun wọn. Ki i ṣe kiki pe ki wọn gbá Tẹmpili nikan ni wọn ni lati ṣe, wọn ni lati ni iyipada ọkàn pẹlu.

Ohun nla ni eyi jẹ́. Lẹyin ipe lati wá si ajọ, a tun gba awọn eniyan niyanju lati yipada kuro ninu ẹ̀ṣẹ wọn ki wọn si yipada si Ọlọrun. Wọn kò ni ri ire ninu Ajọ Irekọja naa bi wọn ba wà ni ipò ẹ̀ṣẹ. Eyi tayọ ipejọpọ nibi ti ọ̀rẹ́ n pade ọ̀rẹ́ lati jumọ ta okú ọ̀rọ sọ. Akoko yii ni lati jẹ́ akoko isin ọ̀wọ̀ ninu eyi ti awọn eniyan yoo wá gbà ibukun Ọlọrun ati lati ni idapọ pẹlu Rẹ̀.

Nigba ti a ba pejọ fun Ajọ Agọ ti i ṣe ipade nla, a maa n ri ibukun gbà lọpọlọpọ bi a ba gbadura ṣaaju akoko yi, ti a si bẹ Ọlọrun lati ṣiṣẹ laaarin wa. Nigba ti a ba pese ọkàn wa silẹ fun àsè ti ẹmi nipa bibá Ọlọrun sọrọ, a o jẹ́ ibukun fun awọn ẹlomiran, awa paapaa yoo si pada pẹlu agbára ọ̀tun.

**Alabukun ninu Ṣiṣe Nnkan Wọnyii**

Nigba ti Jesu dá Ounjẹ Alẹ Oluwa silẹ, eyi ti a n ṣe dipo Ajọ Irekọja O wi pe, "Bi ẹnyin ba mọ nkan wọnyi, alabukun-fun ni nyin, bi ẹnyin ba nṣe wọn." Ayọ̀ a maa jẹ́ ti wa nigba ti a ba pa aṣẹ Ọlọrun mọ́ ni ọ̀na ti Rẹ̀. Paulu Apọsteli kilọ fun awọn eniyan ki wọn má ṣe jẹ Ounjẹ Alẹ Oluwa bi wọn ba wà ni ipo ẹ̀ṣẹ. Eyi yii yoo mú ijiya wá sori wọn. Ṣugbọn nigba ti ọmọ Ọlọrun kan ba wá sibi tabili Oluwa ti o si n ṣe aṣaro nipa alẹ ọjọ naa ti a fi Jesu hàn, oun yoo ri ọ̀pọ ibukun gbà. Ki i ṣe kiki ẹbọ ti Kristi fi ara Rẹ̀ rú nikan ni a ni lati bojuwo ẹ̀yin wò, ṣugbọn a n wọna fun ọjọ naa ti a o ba A jẹun ni Ijọba Rẹ̀.

Hesekiah rán awọn eniyan naa leti ileri ti Ọlọrun ti ṣe fun wọn bi wọn bá jẹ́ ronupiwada. Ọpọlọpọ awọn Ọmọ Israẹli wà ni oko-ẹrú nigba yii. Bi awọn ti o kù yoo ba fi gbogbo ọkàn wọn wá Ọlọrun, Oun yoo mú awọn eniyan wọn pada bọ̀.

Iwọ le ro pe gbogbo eniyan ni yoo ronupiwada ti wọn yoo si bẹrẹsi gbadura nigba ti wọn ri iwe yii gbà. Ireti tun sọji pe Ọlọrun yoo ràn wọ́n lọwọ. Ṣugbọn dipo eyi, wọn fi awọn eniyan ti o mu ihin yii wa ṣe ẹlẹ́yà, "nwọn fi wọn rẹrin ẹlẹya." Ohun kan naa ha kọ́ ni awọn ẹlẹṣẹ n ṣe ni ode-oni.

Ayé kò fi igba kan fẹ́ gbọ́ ti Ihinrere. O dabi ẹni pe ọkàn ọmọ-eniyan kun fun kiki ibi nigba gbogbo; iwọn iba eniyan diẹ ni o n lakàkà lati ri igbala. Wò bi inu awa ti a ti fi ọkàn wa fun Ọlọrun ti a si mọ̀ pe a n reti bibọ̀ wa ni Ọrun ti dùn pọ́ tó! Ayọ̀ awa pẹlu ti pọ̀ tó lati ri i pe awọn ẹlomiran ri igbala!

A ko ṣai ri iwọn iba eniyan diẹ ti o n jẹ ipe Ihinrere ni gbogbo igba ati akoko. Diẹ ninu awọn ti wọn ri iwe yii gbà ni Israẹli ṣetan lati gbọran si aṣẹ Ọlọrun, wọn si wá si Jerusalẹmu lati pa Ajọ Irekọja mọ́.

Awọn ẹya Juda tete tẹwọgba ipe naa ju awọn iyoku lọ. Ọpọlọpọ ninu wọn wá si Jerusalẹmu lati jumọ bá wọn kó iyoku pẹpẹ oriṣa jade ati lati pa wọ́n run.

**Isin Atọkanwa**

Ki i ṣe kiki pẹpẹ oriṣa ni a ni lati wó lulẹ̀ ki a si wẹ Tẹmpili mọ́, awọn eniyan pẹlu ni lati wẹ ara wọn mọ́ fun Ajọ Irekọja. Ṣugbọn àye kò si tó fun awọn eniyan lati pa gbogbo ilana iwẹnùmọ ti ode-ara mọ́ ni kikun, o si ni lati jẹ pe ajakalẹ-arun kọlu awọn eniyan diẹ nitori ti wọn jẹ Irekọja lai ṣe iwẹnumọ ti o yẹ ki wọn ṣe. Hesekiah gbadura pe ki Ọlọrun dári aiṣe iwẹnumọ ode-ara wọnyii ji, ki O si wo awọn eniyan naa sàn. Ọlọrun gbọ́ adura rẹ̀ nitori ọkàn awọn eniyan naa yipada si Ọlọrun, eyi ni si ṣe pataki ju isin ode-ara lọ. Isin atọkanwa ni Ọlọrun n fẹ́.

Igba kan wà ni igbesi-ayé awọn Ọmọ Israẹli ti wọn bojuto gbogbo ọjọ ase ati ilana isin, ṣugbọn ọkàn wọn jinna si Ọlọrun. Ọlọrun sọ nigba naa pe: "Ẹ má mu ọrẹ asan wá mọ́: turari jasi ohun irira fun mi; oṣù titun ati ọjọ isimi, ipè ajọ, emi kò le rọju gbà" (Isaiah 1:13, 14). Awọn eniyan n fẹ lati sin Ọlọrun pẹlu ẹ̀ṣẹ ninu ọkàn wọn. Ṣugbọn Ọlọrun fẹ́ ki wọn jẹ́ mimọ́, "Ẹ wẹ̀, ki ẹ mọ́; mu buburu iṣe nyin kuro niwaju oju mi: dawọ duro lati ṣe buburu; kọ́ lati ṣe rere" (Isaiah 1:16, 17).

**Yiyọ̀ ninu Oluwa**

Ọlọrun gbọ́ adura Hesekiah, O ri i pe awọn eniyan jẹ́ oloootọ, O si tú ibukun Rẹ̀ dà sori awọn ti o ti pese ọkàn wọn silẹ lati wá A. Ọjọ meje ni wọn fi n jẹwọ ẹ̀ṣẹ wọn, wọn si n ri ibukun Ọlorun gbà. Wọn pa ajọ aiwukara mọ́ pẹlu "ayọ nla; awọn ọmọ Lefi ati awọn alufa yin OLUWA lojojumọ, wọn nfi ohun-elo olohùn goro kọrin si OLUWA." Awọn ọmọ Lefi si kọ́ awọn eniyan naa ni "imọ rere OLUWA." "A! ijinlẹ ọrọ̀ ati ọgbọ́n ati imọ Ọlọrun! Awamáridi idajọ rẹ̀ ti ri, ọ̀na rẹ̀ si jù awari lọ!" (Romu 11:33).

Yatọ si igba ijọba Sọlomọni, awọn Ọmọ Israẹli kò layọ to bayii ri. Wọn ti yipada si Ọlọrun wọn si n sin In gẹgẹ bi aṣẹ rẹ̀. Eyi ni orisun alaafia tootọ. Lẹyin ọjọ meje, wọn tun pinnu lati duro ni ọjọ meje si i. Olukuluku eniyan ni o layọ̀ ati awọn alejo ti wọn tilẹ wà ni Jerusalẹmu pẹlu.

Lakotan, asè nla naa pari, awọn eniyan si pada si ile wọn. Wo ire ti wọn ti ri gbà nitori pe wọn wá! Wọn tun fi oju kan ara wọn, wọn si sin Ọlọrun ninu iṣọkan igbagbọ́. Wọn ni ipinnu ọtun lati fara mọ́ isin otitọ, nibikibi ti wọn ba si ti ri oriṣa ati pẹpẹ oriṣa, wọn a wo o lulẹ.

Wọn layọ nitori pe wọn mu ifẹ Ọlọrun ṣẹ. Ọlọrun a maa bukun wa nigba ti a ba jọwọ ohun gbogbo fun Un.

Isọji yii ṣilẹkun igba titun silẹ fun isin otitọ ni Jerusalẹmu. Hesekiah fi idi ijọ kalẹ ati eto isin awọn alufaa, iranlọwọ fun awọn alufaa nipa idamẹwaa, ati ohun gbogbo ti a ni lati ṣe lati sin Ọlorun ni ọ̀na ti o ṣe itẹwọgbà. Gbogbo eyi ti Hesekiah ṣe ni o ṣe tọkàntọkàn, Ọlọrun si mu ki o ṣe rere ati awọn Ọmọ Israẹli pẹlu.

**AWỌN IBEERE**

1 Ajọ wo ni Hesekiah fẹ ṣe ni Jerusalẹmu?

2 Nigba wo ni a kọ́ dá ajọ yii silẹ?

3 O ti pẹ́ tó ti wọn ti ṣe ajọ yii kẹyin?

4 Ki ni awọn Ọmọ Israẹli ṣe lati murasilẹ fun ajọ naa?

5 Bawo ni awọn eniyan ṣe gba ihin yii ni Israẹli ati Juda?

6 Ki ni ṣẹlẹ ni ibi ajọ naa?

7 Bawo ni ajọ yii ti pẹ́ tó?

8 Iru isin wo ni o ṣe itẹwọgbà niwaju Ọlọrun?

9 Ki ni Hesekiah ṣe lẹyin ajọ naa?